# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA

VOL. VI No. 336 MONDAY JULY 9 — JULY 15 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


**owe**

Ina fi Ikoko Sawa, o ngba kurukuru S'omi Abinuẹni ko ti koto tini si. Ohun ti Ọlọrun yio ṣe ko fi han Ẹnikan.

**AKIYESI**

Adu ṣeni wipe a ko le tẹ Ojo Oja Ilẹ wa gẹgẹbi a ti ṣe Ileri ninu Iwe wa Ọsẹ ti o kọja.

Olotu da kan lọ si Ghana lati lo ṣe ibẹwo awọn Asoju "Iwe Irohin Imolẹ" nitorina o di Ibẹrẹ Osu ti mbo ki o to le jade.

*OLOTU*

# OBINRIN KAN SỌ ALE RẸ DI AGẸMỌ

IBADAN:— GBOGBO AWỌN ERO KOTU IJỌBA IBILẸ KAN NI IBADAN, NI O RIN ẸRIN ARINTAKITI NIGBATI NWỌN GBỌ GẸGẸBI ỌKỌLOBINRIN KAN TI ṢE NROJỌ NIWAJU ADAJỌ KOTU NA, NIPA IWA IBAJẸ KAN TI IYAWO RẸ ATI ALE RẸ HU SI INU ILE RẸ.

Nigbati Ọkunrin na bẹrẹ si rojo niwaju Adajọ nipa ẹsun ti Ọlọpa mu wa si kotu pe, on ati iyawo rẹ lu ọkunrin kan ni alupamoku, ọkọlobinrin na ṣe alaye ni kọtu bayi pe,:- Nigbati on fura si i pe, iyawo on ngni ipade pọ pẹlu ọkunrin miran, ni on ba purọ tan iyawo on jọ ni kutukutu owurọ ọjọ kan pe, on nlọ sidalẹ, on yio si de ni ọjọ keji, on si lọ fi ara pamọ si ile kan ni adugbo, ti ko jinna pupọ si ile on.

Kopẹ pupọ lẹhin eyi, ni on ba dari pada wa sile on si ba ilẹkun ti nwọn ti ti i gbọnin-gbọnin. Nigbati on bẹrẹ si kan ilẹkun, on ko tete gbọ esi, ṣugbọn on ngbọ hara-huru iro ẹni-ore ninu ile, lẹhin eyi ni Iyawo on ba silẹkun fun on. Bi on ti wọle lati joko ni on ri ẹni-ore kan ti o ri gidigba, ti nwọn si gbe e duro lẹgbẹ ogiri ni ikangun korọ igun ile.

Lẹsẹkẹsẹ ni on fura si ẹni-ore ti o duro yi, a ṣe Iyawo on ni o ti sọ ale rẹ di Agẹmọ ti o yi ẹni mọ ọ ti o si gbe e ti lara ogiri. bi on si ti nawọ si ẹni yi lati fa a lulẹ, ni ẹni na ba tuka lojiji, Ọkunrin to wa ninu ẹni na si bẹrẹsi ba on ja, o nkan on lẹsẹ, on na si nkan lẹsẹ,. Lẹsẹkẹsẹ ti ija yi bẹrẹ ni Iyawo on ba sare wọle gẹgẹbi alaimọ kan, o si nla awọn ni ija, o nsọ wipe, "o to o, ẹ ma ja mọ, ẹ yee lu'ra nyin, ẹ ma para nyin ẹ yee fara nyin laṣọ ya".

Ọkọ-lobinrin na si sọ pe nitoripe on ti fura si ale-Iyawo on na pe, o nwa sinu ile on wa ba Iyawo on lopọ lẹhin on, ni on ti ṣe lọ sapamọ fun wọn ni ọjọ na, ki on to wa ka wọn mọ ẹnu ibiti nwọn gbe mba ara wọn lopọ lọwọ. Ṣugbọn idajọ ti Adajọ ṣe fun Tọkọ-Taya ni ọjọ na ni pe ki awọn mejeji lọ fi pọun mẹwa (£10) tanran si kotu, nitori nwọn jẹbililu ti nwọn lu Ọkunrin na.

## ROTIMI JARE ẸJỌ

NI ILE ẹjọ nla ti Eko ni ọjọ kẹfa oṣu yi ni, Satide ni awọn adajọ agba Naijiria dajọ pe ahamọ ti Ọlọla Oloye Majẹkodunmi Olotu ti nṣe eto Iwọ Orun nisiyi, ko tọ ọna.

Nwọn ni ofin ahamọ ti o lo fun Rotimi yapa si ilana ati ofin ilẹ wa.

Nwọn ni Rotimi, ko ṣe ju ọlaja lọ. Nigbati rogbodiyan bẹ silẹ, o ko awọn Agba jọ o si sa ipa rẹ gidi gidi lati mu Alafia si arin ẹgbẹ, Awọn Adajọ ni eyi ki i ṣe ohun ti o buru to ki a fi si ahamọ nipa ofin pajawiri.

Oloye Rotimi Williams jẹ ọkan ninu awọn Agbẹjọro pataki ti o wa ni Afirika. Okiki rẹ si ti kan ka gbogbo Agbaiye.

Oloye Rotimi ko si ni ile ẹjọ nigbati nwọn da ẹjọ rẹ nitoripe Oloye Majẹkodunmi ti paṣẹ pe ko gbọdọ kuro in Abẹokuta.

Ṣugbọn Oloye Rotimi kọ iwe si ile ẹjọ. Ninu iwe rẹ o ni ti awọn Adajọ ba da on lare yio wun on ki nwọn fi si iwe akọsilẹ pe on ko bere fun owo idajọ na.

Adajọ agba ọlọla Adekunbọ Ademọla funra rẹ lo ka iwe na ni ile ẹjọ.

## Orun ati Oṣupa fẹ ja

Nigbati Orun ati Osupa ba fẹ koja lara ara won, awon ara Ilẹ Naijiria a ma so lakoko na wipe Orun ati Osupa nja.

Bi a ko ba awon enia pe bẹ, ohun ti a fe so yi ko le ye wọn.

Awon Ojogbọn Aiye fi ye wa be ni Ipari osu ti a bo si yi July 31st Orun pelu Osupa yio ja ni akoko Ọsan gangan. Ṣugbon nwon gbagbe lati fi ye wa boya Ọsan yio di oru tabi ko ni je be ni akoko aṣalẹ tabi li oru ni nwon ma nsaba ja be, Ṣugbon ti Ipari Oṣu yi yio je Ọsan gangan.


ADVRT 109

## IKEDE

OWO ATIJỌ TI WEST AFRICAN CURENCY BOARD

Lati ọjọ kini oṣu July, 1962, eyiti iṣe oṣu keje ọdun yi, gbogbo owo atijọ patapata ni pepa kọrẹnsi ati ṣile pẹlu owo wẹwẹ miran bẹ ti West African Currency Board ti kuro labẹ ofin ni jake jado ilẹ Nigeria. Owo yi ko ni ṣe na mọ fun sisan gbese tabi ki o wu lo fun tita tabi rira ọja ni ṣọbu ati ni ọja. Ṣugbọn owo wọnyi ṣi ni iye lori ati wipe ẹnyin ṣi le ṣe paṣi parọ wọn ni gbogbo bank.

Lati ran yin lọwọ. Central Bank ti Nigeria ti ṣe eto pẹlu gbogbo bank pe ki wọn ma ṣe dẹkun lati ma ṣẹ paṣi parọ owo pepa kọrẹnsi ti atijọ l'ọfẹ fun awọn enia titi di ipari oṣu September 1962, ti nṣe oṣu kẹsan ọdun yi ati fun owo ṣile ati awọn isọngbe rẹ titi di ipari oṣu December, ti nṣe ipari ọdun yi.

Nitorina a bẹ gbogbo yin patapata lati mu owo atijọ ti o mbẹ lọwọ yin lọ si bank ti ọ ba sun mọ yin ki Ẹ lọ ṣe paṣi parọ wọn l'ọfẹ si owo Nigeria titun ti Central Bank fi si ode ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Ẹ ma ṣe jafara.

Gbogbo ẹniti ko ba parọ owo rẹ si owo Nigeria titun asiko ti a fi silẹ fun yin ba fi pari yio san owo fun bank nigbati o ba fẹ ṣe paṣi parọ owo atijọ rẹ lẹhin wọnyi.

*W. A. TABBLES*
*General Manager*

*Central Bank of Nigeria,*
*Lagos.*

## Awọn Ọmuti meji lu obinrin kan pa nitori ife-ẹmu kan

ENUGU:- Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọgbọnjọ oṣu kefa ọdun yi ni awọn ọrẹ meji kan nja si ife-ẹmu kan ti o ku ninu akeregbe ẹmu na wipe "Emi ni ngo mu eyi ti o ku", "Iwọ kọ ni o mu" "emi ni", ti awọn mejeji si bẹrẹ si fa ife ẹmu na mọ ara wọn lọwọ, ti nwọn si fa aṣọ ya mọrawọn lara.

Nibiti ekini gbe ti nwọ aṣọ rẹ ti o faya, ni ekeji ba tete sare mu ẹmu na, lojiji ni eyi ti aṣọ rẹ faya ba lọ mu irin kan, bi o si ti ni ki on ju lu ẹnikeji rẹ, ni irin na ba ṣeṣi ba ọbinrin kan, Nwankwo Nnamani, ti o ngbe Akpugo, ni agbegbe Enugu.

Obinrin na nkojalọ ni akoko na ni, irin na si ba ni oju o si ṣubu lulẹ lojiji. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn si gbe obirin na lọ si ile Iwosan Enugu, ṣugbọn o ti ku ni ile iwosan na.

## Ọmọ ile-iwe kan pokunso

OSUDU:- Idamu ba gbogbo awọn ara Ogbudu ni agbegbe Ogoja nigbati nwọn ri ọmọ ile-iwe kan, Adamu Okene, ẹni ọdun mẹtadinlogun ti o pokunso ninu igbo kan ti ko jinna si ile-iwe wọn ni ọjọ Ojobọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi. Ko si ẹniti o mọ ohun ti o ṣe ọmọde na ki o to pokunso. Awọn Ọlọpa ti gbe oku rẹ lọ si ile - Iwosan Lakulaku, nwọn si nṣe iwadi iku rẹ.

## Oloye Awolọwọ pada si ilu rẹ



IBADAN:- Oloye Ọbafẹmi Awolowọ Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Olori Ẹgbẹ Alatako ninu Ile Igbimọ Apapọ Ijọba, Naijiria ti pada si ilu rẹ Ikẹnnẹ, lẹhin ti o ti gbe Lẹkki fun ọjọ mẹtadinlogun.

Ni ọjọ kọkandinlogun oṣu ti o koja yi ni Alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Dọkita Majẹkodunmi fi iwe aṣẹ gbe Oloye Awọlọwọ ati Oloye Akintọla kuro ni ilu wọn.

Ṣugbọn Oloye Awọlọwọ ko gbọdọ rin koja Ibuso kan abọ dipo ibuso mẹta ti nwọn ti fun tẹlẹri.

# Yẹyẹnatu!

## ONI YẸYẸ EKO

Olotu— Yẹyẹnatu, Halo o
Yẹyẹnatu:— Ki lẹ fẹ lo?
Olotu:— Mi ki rẹ ni kẹ. Ṣebi o lo gboyinbo.
Yẹyẹnatu:— Oyinbo wa lẹ fọhun hun?
Olotu:— O dara ma binu. Jẹ ka ma gbaladun.
Yẹyẹnatu:— Hẹn-hẹn aṣe otitọ ni.
Olotu:— Otitọ ni kini, gbogbo nkan tirẹ lo kuku nyatọ.
Yẹyẹnatu:— Bi o le ya Ijọra ko ya Ijọra. Emi ko mọ pe bi a ṣe nijọ nṣo to yi ẹ ko fẹran mi
Olotu:— Kilo wa fa gbogbo iyẹn nisisiyi?
Yẹyẹnatu:— Ẹnyin ko mohun tẹ sọ ni
Olotu:— Ṣe nisisiyi?
Yẹyẹnatu:— Yẹs.
Olotu:— Mi ni jẹ ka ma gbaladun.
Yẹyẹnatu:— To ba jẹ ọmọ tiyin ni Ladun, ṣe ẹ ni ka ma gba? Tabi ẹ ko mọ pe ọmọ Iya mi ni Ladun ni?



Olotu:— Yẹyẹnatu, hun-hun, mi tilẹ ṣe bi o siriọsi ni
Yẹyẹnatu:— Lagbara Ọlọrun nko ni siriọsi laiyelaiye, ẹni siriọsi wa ni Ikoyi.
Olotu:— Tilẹ gbọ, ṣebi ọrẹ rẹ ba wọn ṣe Mis Legọsi? Ko yọ ni?
Yẹyẹnatu:— Ṣẹ ri awọn oni Mis Legos yẹn, ori wọn pe
Olotu:— Hẹn - hẹn.
Yẹyẹnatu:— Ẹ ko mọ nkan ti Adija ṣe ni?
Olotu:— Sọ ọ ka gbọ kẹ.
Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ mọ pe Adija ko ni ọyan ati idi?
Olotu:— Hẹn mo mọ, ṣugbọn mo ri i pe o ni idi ati ọyan ninu fọto ti mo ri ninu Dele Taimus. Yu si, o ya mi lẹnu gan ni
Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ ri, fọto yẹn ni awọn oni Mis Legos ri ti nwọn pe si ipade awọn to ku.
Olotu:— Lo ba lọ
Yẹyẹnatu:— O lọ kẹ
Olotu:— Tabi iwọ na lọ?
Yẹyẹnatu:— Ayi lọ ti jẹ Ti mi tilẹ jo gan papa.
Olotu:— Hẹnhẹn, kilo wa de si ọrẹ rẹ?
Yẹyẹnatu:- Hẹnhẹn, ṣẹ ri nwọn ti npe gbogbo wọn o, igbati o ya ṣa ni mo gbọ ti nwọn pe " nọmba fifti - twẹlfu" l'Adija ba jade.
Olotu:- Ha - ha - ha
Yẹyẹnatu:- Mo rẹrin, rẹrin. Aṣe nko yi ri ẹrin. Nigbati o yan lọ ti o yan bọ, lobinrin kan sunmọ pe ki on ka aṣọ rẹ ki gbogbo enia ri itan rẹ, ni bebe, nla ti o di sidi ba jabọ.
Olotu:- Ha-ha-ha, oni bebe.
Yẹyẹnatu:- Bo ṣe bẹrẹ pe on fẹ mu bebe, ọyan Kinswe ti o so maya tun ja. Lariwo ba ta.
Olotu:- O maṣe o, ye-yeye. Oju mi nṣomi o jare
Yẹyẹnatu:- Ha - ha, Olotu, ṣe ntori ti Adija na lẹ ṣe nṣọkun.
Olotu:- Yẹyẹnatu, bọ sita ma lọ, ma pa mi,
Yẹyẹnatu:- O dara, o dabọ o

## Awọn Ọmọ Ifẹ to wa l'Eko sọ wipe awọn nigbẹkẹle si Ọni

Awọn ọmọ Ọba Ile-Ifẹ ti o wa ni Eko, Ebute-Metta, Mushin, Yaba ati Shomolu ṣe Ipade alabẹṣekele ni Kadara Street, Ebute-Mẹtta ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi.

Alaga Ipade na sọ wipe ohun ti o mu on pe Ipade na ni Irohin kan ti awọn ngbọ wipe awọn kan ni (Ile Ifẹ) sọ wipe ki Ọlọla Adesọji Aderẹmi Ọni–Ifẹ kuro lori Itẹ Oye

Nwọn ni awọn ọmọ Ọba Ile Ifẹ ti o wa l'Eko ko fara mọ eto na. Gbogbo wọn si gba wipe ki Ọlọla Adesọji Aderẹmi wa lori Oye rẹ, awọn ni igbẹkẹle si ki o ma ṣe bẹru.

# IFẸ LOJU (APA KẸTALA)

LATI ỌWỌ:— Afolabi Olabimtan

Gẹgẹbi mo ti ṣe ileri fun yin ni ọsẹ to kọja pe ẹ o ma gbọ ohun ti Baba Muli ṣe nigbati o ri pe ọmọ rẹ ti di Onile, Ọlọna ti gbogbo Ilu si mọ ọ. Ni akoko yi inu Baba Muli tu, o yọnu si ọmo rẹ. O si gbiyanju gidigidi lati fa mọra, ki oju ma ba ti pupọ, niwọn igbati o ti kọ ẹbẹ ni akọkọ, O ni on yio d a r i j i nisisiyi "Nitoripe Iya rẹ ti di Oku Ọrun, ko si ni ẹlomiran mọ a fi emi nikan. Ni kukuru, Igbega Muli fa Baba rẹ mọra pada, Oluwa tu inu rẹ ka, O yọnu si Tọkọ Taya, o si di kori-kosun wọn.

Muli fẹran Iyabọ pupọ nitoripe, o jẹ obinrin, kiṣe w i p e o korira ọmọ rẹ Ọkunrin ṣugbọn I f ẹ rẹ si Ọmọbinrin pọ ju ti Ọkunrin lọ.

Gẹgẹbi o si ṣe ma nsẹlẹ, bi Iyabọ ṣe ndagba si bẹ ni ibẹru to ni fun Iya rẹ ṣe ndinku si, ṣugbọn ibẹru ti Baba rẹ tun npọ si i. Ifẹ ti Iya rẹ ni pọ tobẹ gẹ to ma fi nfi ọpọlọpọ jin. Nida keji Baba rẹ ko fi oju rẹ balẹ, nitori o gbagbọ pe ti on ko ba mu ina soju, ọmọ on obinrin yio ya iyakuya

Nigbati Iyabọ di ọmọ ọdun mẹdogun iṣẹ gbe Baba rẹ kuro nilu, o si lọ si Abẹokuta, ko to lọ silu yi, owo Muli ti gbinlẹ bi Ogẹdẹ, Aje ti ji si lọwọ, Iranwọ rẹ ti tan, Iyabọ si wa ni iwe kẹjọ ti Oyinbo. Ni kukuru o h a n gbangba pe Ojogẹ ko le lọ pẹlu Iyabọ ati awọn Ọmọ.

Ni igbẹhin Baba Iyabọ di ẹru, o gbọna Abẹokuta, lakọkọ, bi o ṣ u meji, ayun ile nyun Ojogẹ. nigbagbogbo lo ma nfẹ l a t i ba Iyawo tabi awọn Ọmọ rẹ sọrọ, ọpọlọpọ igba lo si ma nfẹ lati ma ṣe orisirisi nkan bi o ṣe nṣe nile.

Ifẹ rẹ si I y a w o rẹ ko ṣa kere, bẹni ti Iyawo rẹ si on ko ṣe wọn, tọtun tosi n w ọ n lo kun fun Ifẹ ara wọn.

Gẹgẹbi Oṣiṣẹ enia, gbogbo Ọga ti Ojogẹ ba nilu yi ni o fẹran rẹ, o ni Itẹriba, o ni ọyaya, ọmọ Oluwabi si ni Ojogẹ nṣe, ko to ọjọ ko to oṣu, ti Ojogẹ de Ilu yi, awọn fun ni igbega ni ibiṣẹ, O tẹ waya si Iyawo rẹ nile, inu gbogbo wọn si dun, ṣugbọn eyi ko ni ki Ojogẹ ni Igberaga rara si awọn ẹlẹgbẹ rẹ, o nbọwọ fun Agba, ko nyaju si Ọmọde, ko si nta awọn ẹlẹgbẹ rẹ nu, o mọ ọwọ rẹ ni ọwọ, o si mọ Agba ni ẹgbọn, o nfi Ọla fun awọn ti Ọla ba nṣe ti wọn.

Iru iwa bayi jẹ ki gbogbo enia fẹran Ojogẹ nilu, ẹnikan ko sọrọ rẹ nibi, o di iriju ọ m ọ d e, o di ọrẹ agbalagba, gbogbo Wundia nfẹ ki Ojogẹ jẹ Ọkọ awọn, ọpọ Adelebọ lo ni ifẹ Ojogẹ, dede Ọmoge lo nfẹ ki B a b a Iyabọde jẹ Ọkọ awọn. Ṣugbọn Iya Iyabọde wa nile, Muli Aya Ojogẹ nbẹ, Baba Iyabọ ko fẹ ba Aya rẹ ninu jẹ, ko gbagbe gbogbo ohun ti oju wọn ti ri, bẹni ko ṣai ma ranti Iya ti Muli jẹ nitori on.

Ẹ o ma ka apa Kẹrinla Itan mi yi lọsẹ to m b ọ lagbara Oduduwa. O di gba kan na.



Aworan ti a nwo loke yi ni ti awọn enia Jankan-Jankan ti wọn wa sibi aṣe Apejọ ti Aṣoju ilẹ Kongo (Congo) ni N a i j i r i a pe laipọ yi lati ṣe iranti ọdun keji ti ilẹ Congo gba Ominira.

Ẹniti o wa lẹgbẹ osi to wọ ẹwu funfun ni Dokita E. A. Ẹsin, ẹniti o duro ni arin wọn ni Ọgbẹni F. C. Nwekedi. Awọn mejeji wa lẹ Asoju ilẹ Congo nilẹ Naijiria wo, on na ni Ọgbẹni G. Bahise to wa ni apa ọtun.

# IWE SI OLOTU

## Mushin nfẹ Ẹrọ-Omi

Mo toro gaafara lọdọ Olotu iwe Irohin Imọle, lati kesi Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria pe ki nwọn fun wa ni Ẹrọ-Omi ni i l u Mushin. Aini Ẹro-omi ni ilu na ngmu opolopo ifaschin ba wa ni ilu na.

Agbara Ojo si ti ba opolopo omi inu awon Kanga je kakiri ilu. Nṣe ni gbogbo re kun fun idoti, koda omiran ko ṣe e mu rara.

Nitorina inu mi yio dun bi Ijoba rere na a ba le gba oro yi yewo, ki nwon si tete ran wa lowo nipa re.

Emi ni
Samuel Adeyemi Ọlawepo

MUSHIN

## E ba wa da Oda de arin ilu Shomolu

Olotu/ Mo fi iteriba ati owo kesi Ijoba Ibile Mushin pe ki nwon ba wa da ọda ti nwon da si titi Shomolu de arin Shomolu.

Ti Ijoba na ba le da Oda yi si i tan, yio je ohun idunnu gbogbo awon ara ilu na, ibiti nwon da Oda na de wu ettikeni lori pupọ. Bi ọda na ba le de arin ilu a dara pupo, moto yio si tun rọrun fun awọn Oṣiṣe ati awọn Oniṣowo ti nwon ng wọ Mọto jade ni ilu Ṣhomolu lọ si Eko tabi Idale.

Olotu mo dupe aye ti e gba mi, Ọko Ọba ko ni ṣa yin lese o.

Emi ni
LAWAL BELLO

SHOMOLU

## Ẹ LA EYI YE MI?

OLOTU, Jọwọ gba mi laye lati bere ibere yi lọwọ awọn Ọnkawe iwe Irohin Imọlẹ.

Ibere na ni pe, a ma a nri i ka ninu Bibeli wipe "Ibukun ni fun awọn Onilaja nitori ọmọ Ọlọrun ni a o ma a pe wọn" eyi jẹ ofin tabi aṣa ti o sọpọ larin wa lati ma a ba ara wa fi sọrọ nigbagbogbo.

Ṣugbọn, iru ibukun wo ni o mbẹ fun awọn ẹniti o laja ti nwọn si fi ara gbọgbẹ ati ẹniti o laja ti o ti ipasẹ e y i de ọgba ẹwọn tabi ti o fi owo tantan ẹsun ti nwon ba mu u fun?

Mo nreti esi o.

Emi ni
Eko OYETUNJI ADEỌSUN

## Mushin nfẹ iranlọwọ Ijọba

Olotu/ jọwọ gba mi laye ninu iwe Irohin Imọlẹ" oloyinmomọ nyin lati kesi awọn Alamojuto Ijẹba Ipinlẹ Iwọ Orun lati ba wa tun oju ọna mọto ṣe ni Mushin.

Awọn ọna na ko dara fun mọtọ rara, bẹẹi ojojumọ ni mọto npọ si ni ilu Mushin. Awọn ọna miran si ti bajẹ ti ko ṣe gba fun mọto rara.

Ẹ tete ba wa moju to awọn oju ọna Mushin.

Emi ni,
JAMIYU KỌLA JUBIRILA,
MUSHIN.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## ORE LOPE IKA KOPE (Apa 1)

LATI ỌWỌ:— S. A. IDOWU
No. 126, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ni igba kan, Ọba kan wa ti o bi ọmọkunrin mẹta, orukọ awọn ọmọ na a si ma jẹ bayi: Kunle, Jinmi ati Ọlaitan. Kunle ati Jinmi jade kuro nile lati lọ wo bi aiye tiri, ṣugbọn laipẹ nwọn wa de ipo to jẹ pe nwọn ko le lọmọ, wọn kosi tun le pada sile. Lẹhin na ni Ọlaitan to jẹ aburo wọn pata-pata na wa mura lati wa awọn ẹgbọn rẹ Kunle ati Jinmi lọ. Ṣugbọn laipẹ o ri wọn. Nigbati o ri wọn, yẹyẹ ni wọn fi nṣe, ohun to fa yẹyẹ ti wọn fi ṣe nipe wọn ni awọn ti awọn dagba tawọn tun ni ọgbọn ju ẹ lọ ko le lomo, wọn gbagbe owe awọn agba to sọ pe "Ọmọde lọgbọn, Agba lọgbọn" Gbogbo wọn mura wọn lọ si irin ajo na, laipẹ wọn de ibi ile awọn Ikan. Awọn ẹgbọn rẹ mejeji Kunle ati Jinmi nfẹ lati wo ile awọn Ikan yẹn, ki awọn le ri wọn bi wọn ti ṣe ma ma du kakiri. Ṣugbọn aburo wọn Ọlaitan ko jẹ o ni ẹ fi wọn silẹ kẹjẹ ki wọn ma jẹ aiye wọn. Wọn fi wọn silẹ wọn si mba ọna wọn lọ, laipẹ wọn de ibi ti awọn Pẹpẹiyẹ ti nwẹ wọn fẹ mu meji ninu wọn ki wọn pa wọn, ṣugbon Ọlaitan ko jẹ, o ni ẹ fi wọn silẹ ki wọn ma jẹ aiye wọn, ẹ ma se pa wọn.

Laipẹ wọn tun de idi igi oniho ti awọn Oyin wa, wọn fẹ danọ sun wọn ki wọn ba le ko oyin to wa nibẹ ṣugbọn Ọlaitan ko jẹ, o ni ẹ fi wọn silẹ, ẹ ma ṣe danọ sun wọn, ẹjẹ ki wọn ma jaiye wọn. Laipẹ wọn tun de ago awọn Ẹsin, Ẹsin to dara pọ ni bẹ ṣugbọn wọn ko ri ẹnikẹni nibẹ, wọn bẹrẹsi wọ gbogbo awọn Iyara to wa nibẹ ni kọkan titi wọn fi de ibi kan to jẹ wipe kọkọrọ mẹta ni wọn fi ti, larin ilẹkun na Jigi kan wa nibẹ to jẹ pe wọn le ma ti ibẹ ri yara yoku. Nibẹ ni wọn ti ri Baba arugbo kan to joko lori Tabili. Wọn pe lẹkini, lẹkeji ṣugbọn ko gbọ, nigbati o di ori ẹkẹta o gbọ o si jade wa ba wọn.



Awọn mejeji ti a nwo ninu aworan yi dabi, Olukọtun ati Ajagunna. Orukọ enia Dudu ti o wa ninu aworan yi ni Houphouet Boigny ti iṣe Basọrun ilu Ivory Coast (President) Ẹni keji ti o jẹ oyinbo ni Ọgbẹni Harold Macmillam ti iṣe olori awọn Oṣelu ti Gẹsi. Nwọn ya aworan yi nigbati nwọn nṣe Basọrun ni alejo.

## Itan awọn Alaigbọran ọmọ Ekute

Lati Ọwọ:- IBRAHIM ỌLAITAN
No. 339 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ni igbakan Ọkunrin Agbẹ kan kọ ahere kan sinu oko rẹ kio le ma raye simi lẹhin iṣẹ, nitoripe ohun jijẹ bi agbado, isu, pọ ninu ahere na, bayi ni Ekute nla kan gbẹ iho sinu rẹ o si bi ọmọ marun sinu rẹ.

Ni ọsan ati ni oru nigbati ko ba si Agbẹ na ninu ahere rẹ mọ, ekute yi pẹlu awọn ọmọ rẹ a ma wa jẹun nibẹ nipa bayi nwọn saura dada. Ṣugbọn awọn ọmọ ekute na ya alaigbọran pupọ ọpọlọpọ igba ni iya wọn ma nkilọ fun wọn pe ki nwọn maṣe ohun kan to jẹ pe iyẹn gan ni nwọn yio ma ṣe. O sọ fun wọn titi wọn ko gbọ. Ni ọjọ kan ekute na yọju lati inu iho rẹ lati wo boya Agbẹ na wa ninu ahere rẹ, o si ri ẹranko kan to jọ ologbo nrin kakiri ninu igbo ahere na, nitorina o yara lọ sọ fun awọn ọmọ rẹ pe ki nwọn maṣe jade lọ sibikan lai sọ fun on, nitope ewu wa lode, lẹihn to sọ bẹ tan o fi awọn ọmọ rẹ silẹ o si lọ sun, kopẹ lẹhinna ni ọmọ Ọpọlọ wọle lati pe awọn ọmọ Ekute lati sere lọ awọn ọmọ ekute na si mura lati lọ lẹsẹkanna laikogba asẹ́lọwọ iya wọn, sugbọn eyi to kere ninu awọn ekute na kọlọ ran wọn leti ọrọ ti iya wọn sọ fun wọn sugbọn ẹrin ni nwọn fi urin nwọn ni bi ewu ba wa nita gẹgẹbi iya awọn ti wi, ọmọ Ọpọlọpọ ki yio le wa si ọdọ awọn wa sire laiko ri iyọnu. Ologbo gbọ iro wọn nigbati nwọn mbọ, o rọra fi ara rẹ pamọ titi nwọn fe jade ti nwọn si bẹrẹsi jẹun. Lẹhina Ologbo yi fo mọ wọn lojiji, o si pa awọn ọmọ ologbo mẹtẹta na, ẹkẹrin ti ko pa ṣẹ lẹsẹ nitori o du on na barabara a fi ọpọlọ nikan ni o lọ ni alafia nitori ologbo ki jẹ Ọpọlọ.

Ẹkọ ti o wa ninu itan yi ni pe ibi lo ngbẹhin aigbọran Iwe-mimọ sa ti so wipe igbọran sanju ẹbọ lọ.

Awọn obi wa ko jẹ tan wa jẹ o si yẹ ki awa na tẹle ohun ti wọn ba nsọ fun wa;

## OWE

Lati ọwọ:- JAMIYU K. JUBIRILA
No. 358 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

1. Arugbo ẹru ki jọfẹ, otoṣi Ọba ki nsingba, Iwọfa ti ko i ti ku koi sanwo kogbọ sọ pe on ko ni sin olowo
2. Wẹ ni wọn, aje ni nwẹ ni mọ ṣaka
3. O ri oko Ikun nilẹ o gbin Ẹpa si
4. Loju-loju la nwo o jẹun, lẹnu-lẹnu la nwo Oṣọrọ.
5. Ọtẹ ni mu ni pe Aja ni ifadeyi cruko, ọmọ Awo ni nṣe

## Kini Ohun ti o mo nipa ile Naijiria?

1. Tani Ajele fun ohun ogbin ati iṣura ile fun Ipinle Iwo-Orun
2. Ọjọ wo ni nwon bura fun awon Oluwadi ti Ijoba Apapo Naijiria ynn lati ṣe iwadi nipa bi ijoba Iwo-Orun tiṣe nna owo?
3. Daruko awon Oluwadi na?
4. Tani Alamojuto fun eto ilera ni ila Orun?
5. Ile iṣẹ Ijoba Iwo-Orun melo ni nwon yio ṣe iwadi nipa owo won, Daruko meta ninu won?
6. Kini ohun ti o ṣele ni ile Naijiria ni ojo Ketala oṣu Karun odun yi (13/5/62)
7. Ọdun wo ni a bi Ọgbeni H. A. A. Dotherthy?
8. Odun wo ni Kosuko di Oloye Palma ati Lekki?
9. Ọjọ wo ni orile ede Congo gba Ominira?
10. Tani Alakoso ijoba Congo nigbana (President)?
11. Ninu oṣu wo ni ija besile ni Congo?
12. Ọmọ Ọdun melo ni Lumumba ki nwon to pa?
13. Daruko ilu meji ti o ran awon omo Ogun ilẹ won lo silẹ Congo lati lo la ija?
14. Tani Asoju fun ilẹ Naijiria ni ilu New York?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI LOJU EWE 7

## Oju Kokoro lo npa Ọmọ Araiye ti Ọga ile iṣẹ lo bu:ya

Lati ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Gbogbo ẹnyin ọmọ Ọlọrun, ẹ gbọ ọrọ yi na alanu ko si mọ ẹlẹtan loku, ọpọlọpọ awọn olowo wọn ko fẹ lati ri talaka si oju, Oju kokoro nwọn pọju. Oju kokoro aja ni lọ, nitorina gbogbo ẹnyin talaka ti ẹ ko ba fẹ tiju, ẹ mura lati duro si aye ti Oluwa ba fun yin, gbogbo ẹnyin Ọga iṣẹ ati Dairẹkitọ ti ẹ wa nipo ibiṣẹ g i g a mọ daju wipe bi iwọ ba ni owo lọwọ ti iwọ si nfi mọto ṣe ẹsẹ rin, Iwọ ko fẹ lati mọ ẹnikan mọ rara, ẹ fẹran lati ma kọ iwe ika lati da talaka duro lẹnu iṣẹ na ẹnyin ko mọ ẹhin ọla ipo kipo ti iwọ ba wa mọ daju wipe o le bọ lọwọ rẹ lọla Ha! Ika ko yẹ ọmọ enia rara.

Ṣe iwọ nikan lo fẹ jẹ ile Aiye yi mura lati ma jọla ti Ọlọrun ko fun ọ, mọ wipe ile ti Ọ l o r u n ko ba kọ enia ti nkọ ile na nṣe iṣẹ lasan ni ORIN DAFIDI 127 ẸSẸ 1.

Owo ti yin ko to yin Ẹnyin nikan ni ẹ fẹ kọ ile ẹ fẹ ra Reluwe jọwọ manija ṣora rẹ oju kokoro lo npa enia gbogbo owo olowo ati ipo ti ki iṣe tirẹ lo gba tan iwọ yio si ma mu iwọ yio si ma jẹ iwọ yio si ma rọbi ẹsẹ iwọ yio si loyun iwa ika iwọ yio si bi eke jade.



ORIN DAFIDI 7, ẸSẸ 14, Manija kan ko le ru biriki lọ sọrun lọ ko ile lọhun bẹni olowo kan k o le ku ki nwọn fi mọto ṣe posi rẹ ka ma ri ẹniti nṣe alaisotọ ko ma nṣo ati ẹniti nṣe alẹgbin ko ma ṣe nṣo ẹniti nṣe olodo ko ma ṣe nṣo.

Kiyesi emi mbo kankan ere mi si mbẹ pẹlu mi lati han fun olukuluku gẹgẹbi iṣẹ rẹ yio ti ri, IFIHAN ORIN 22, ẸSẸ 11.

Yọyọ lenu araiye, araiye ko duro de ẹnikan ti a r a wọn ni wọn ngbọ nitorina maṣe duro de Aiye duro de Ọlọrun ẹlẹda rẹ yio si gba ọ Ha! Inu Oluwa ko dun si enia buburu maṣe binu rara ifẹ ti Oluwa ni kaṣe ibukun ni fun ẹniti o nṣe anu yio si ri anu gba lọwọ ọlọrun

Gbogbo ọpọlọpọ Manija ati ọga ati Dairẹkitọ ti ẹ wa ile aiye mọya ti ẹ si tun wa iṣẹ mọya ẹ o si tun loyun ijọgbọd ẹ o si bi poporo Ẹ o gulẹ si ebute ofo nitoripe ẹnyin ko ni oju anu bẹni ISAIAH ORIN 33 ẸSẸ 11. Efi iṣẹ rere tun igbesi aiye yin ṣe tọju iwa rẹ bi iwa rẹ ko ba di ọ lọwọ ko si ẹnikan to le dina ire rẹ ni ile aiye yi Aṣeju ni baba ẹṣẹ Jesu ṣanu fun mi ki emi to lọ laiye yi oṣi ni baba itiju maṣe doju ti mi Oluwa mi Amin.

## IJAMBA ṢE OLE, ONILE KA A MỌ

IBADAN:- Awọn Ọlọpa mu Ogboju O l e, kan, Tiamiyu Rasaki ẹni ọdun mejilelogun, ti awọn Ọlọpa sọ wipe ko ni Ibugbe kan ati wipe, o si ti lọ si ẹwọn fun Igba mẹta ri, wa siwaju Adajọ Kọtu I j ọ b a Ibiẹ (Customary Court) Ibadan ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kẹfa ọdun yi fun ẹsun ole jija.

Ẹjọ ti Ọg b e n i Samson Adigun ti o ba Ọdaran na ṣejọ ro niwaju Adajọ ni pe on ba Ọdaran n a nibi ti o gbe nji aṣọ ti ogbẹni Amos Ogunlaja sa si ori okun lẹhin kule rẹ eyi ti iye owo rẹ jẹ Pọnun m ẹ t a abọ (£3 10/-) ni ọjọ kẹdogbọn oṣu karun ọdun yi ni on ba kiabe ole le e, bi o si ti nsa lọ ni ọ w ọ ba t ẹ ẹ on si mu lọ si Teṣan awọn Ọlọpa.

Adajọ bere lọwọ ọdaran na pe kini ẹjọ t i r ẹ ti jẹ Ọdaran na si sọ wipe on gba pe on jẹbi ẹ s u n na a ṣugbọn on bẹbẹ pe ki Adajọ dariji on nitori aiko ni iṣẹ lomu on jale ni Adajọ ba ni ki o lọ si ẹwọn oṣu m ẹ r i n lafarabara.

## Ọkunrin kan ṣeeṣi gun iyawo rẹ lọbẹ

SAPẸLẸ:-

Pẹlu omi loju ni Okunrin kan ti orukọ rẹ nje Thomas Efejoma fi nrojọ niwaju Adajọ kotu kekere kan ni ọjọ Alabameta tiṣe ọgbọn ọjọ oṣu kefa ọdun yi fun esun pe o ṣeesi gun iyawo rẹ lọbẹ.

Alaye ti Ọlọpa ti o ba odaran na ṣejọ ṣe niwaju Adajọ ni pe nigbati odaran na ṣe Akiyesi wi pe Okunrin kan pe iyawo rẹ o si mu wo inu iyara le lati ba lopọ ni dajran na ba lo mu obe ti o mu dadara o si yo kelekele wo inu iyara ti okunrin na ati iyawo rẹ gbe ugbadon ara won

Nighati iṣe ti wo, okunrin na ati Iyawo rẹ lara, bi o si ti ni ki on gun Okunrin na lobe, lojiji Iyawo rẹ ni obe na ṣeesi gun

Adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kejidilogbon oṣu yi.

## WO ỌMỌGE TI O DARAJULỌ L'EKO FUN ODUN 1962



Ẹniti a nwo yi ni Omidan Yẹmi I d o w u ti o nṣiṣẹ ni Ile iṣẹ Alaṣẹ fun eto Ilera nilu Eko (Federal Minisry of Health) On lo fi ẹwa rẹ yege ninu idanwo awọn Arẹwa ọmọge ilu Eko lọjọ Sat de (Saturday) tiṣe ọgbọnjọ oṣu tokọja fun Arẹwa Ọmọge ọdun 1962.

Yẹmi Idowu jẹ ẹni ọ d u n mejidinlogun, o si ngbe Opopo McEwen Street ni Yaba, Ibiti wọn gbe ṣe afihan Ọmọge Arẹwa ọmọ Eko, (Miss Lagos) ni ile iṣẹ ibiti nwọn gbe nṣe Ọti 7 up ni Apapa.

# Obinrin ti o ji Ọmọ gbe Wẹwọn Ọdun mẹta

IBADAN:- Ni ọjọ ti Eti iṣẹ Ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni Adajọ Agba Ile Ẹjọ giga Ibadan ṣe Idajọ ẹwọn ọdun mẹta fun Ọdaran kan Sariyu Adaeni ẹni ọdun mọkanlelogun fun ẹsun pe, o ji Ọmọ Iyawo Ẹgbọn rẹ gbe.

Ẹjọ ti Ọlọpa ba Ọdaran na ro ni kotu ni pe Ọdaran na lọ si ọdọ Iyawo Ẹgbọn Ọkọ rẹ, Muyinatu Amọpe lati lọ ki i ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu kọnkanla ọdun ti o kọja yi nigbati Iya Ọmọ titun na Muyinatu Amọpe jade lọ si ta lati fọ awọn aṣọ, ni Ọdaran na ba yọ kẹlẹkẹlẹ lọ s i n u Iyara ti ọmọ titun na wa o si gbe s a l ọ nigbati o gbe ọmọ na tan o salọ si ọdọ ọkọ ti o ti kọ s i l ẹ Ọgbẹni Adebisi Akanbi ti o ngbe Abule Kitibi ti ko jina ju Ibusọ mẹdọgbọn lọ si Ibadan o si sọ fun un pe, 'Ọmọ ti mo bi fun ọ niyi wo o', lẹsẹkẹsẹ o ti tọju Ile o si tẹ ọmọ na silẹ lọdọ ọkọ rẹ atijọ, nigbati ọkọ na fura ti o mọ pe ko loyun ki o to kuro lọdọ on, bẹni on ko ri oyun ninu rẹ. Nigbogbo Igba ti on nri i lẹhin igbati o kuro lọdọ on, ni o ba lọ si Tẹsan Ọlọpa, awọn Ọ l ọ p a si mu wa si Kotu.

Adajọ na bere lọwọ Ọdaran na a pe kini ẹjọ tirẹ ti jẹ Ọ d a r a n na si wipe nigbati on ti m b a ọmọ na sire ninu iyara kọ pẹ pupọ ti ebi fi npa on ni on ba fi pọn ọmọ na lọ lati lọ ra nkan ti on yio jẹ, ṣugbọn on ko mọ ọna lati pada sile mọ.

Ni Adajọ ba fi ṣe Idajọ gẹgẹbi a ti wi ṣiwaju.

---

EBRE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

RICHALET FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lati enia o si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buburu ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyen ṣe e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ile yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irafẹ awọn gbogi ba wọnyẹn nama ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse, ati ti a w ọ n Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ. Lakuregbe, orisirisi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ-iba, aroṣ-Edọki, Aya didun Tanpara ati Ekuru laya.

Ara riro, Lapalapa, Egbo Eṣẹ Amodi Apo Ile ito, ẹhin didun tabi ibiradi rro pẹlu. Egbogi Risalẹti a ma a gbogbo kokoro buruku ti o wa n i n u ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Sa dan Igo rẹ kan wọ lara rẹ daju daju wọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran p ẹ l u nigbakugba.

Bere Iodo awọn:-

**Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos,
Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA.

# Obinrin ti o lọkọ meji wẹwọn Oṣu Mẹsan

KADUNA:- Lenulọlọyi ni Alikali Kotu Ijọba Ibilẹ Kaduna ju Ọdaran Abileko Obinrin kan, Aishatu Tundun Wada, ẹni ọgbọn ọdun si ẹwọn oṣu mẹsan nitori o jẹbi ẹsun pe, o ni ọkọ miran laitikọ ọkọ rẹ Malamu Muhammadu, ti abule Tundun Wada, lẹba Kaduna silẹ, o si lọ sile ọkunrin miran laigba Iwe-aṣẹ Ikọsilẹ lọdọ Ijọba

Alaye ti Ọlọpa ti o ba Ọdaran na sejọ ṣe n i w a j u Alikali ni pe, o di ọdun mẹfa ti Ọdaran na ti so yigi pẹlu ọkọ rẹ gẹgẹbi aṣa Musulumi, ko si bimọ rara fun ọkọ rẹ, ṣugbọn nigbati nwọn ṣe gbolohun-asọ ni ọjọ kan ni Ọdaran na ba binu ko ẹru rẹ kuro ni ile oniyigi rẹ o si ko ẹru rẹ lọ si ile ọkunrin miran k a n, Malamu Yahya ti nwọn jijọ ngbe abule kanna, o si fẹ ẹ gẹgẹbi ọkọ.

Nibiti ọkọ rẹ gbe nwa a kakiri, ni o ba rii ninu ile Malamu Yahya, o si pe Ọlọpa mu awọn m e j e j i.

Nigbati Ọdaran na rojọ, o gba wipe on jẹbi, ṣugbọn o bẹbẹ pe ki Alikali darijin on. Alikali si ṣe idajọ pe ki Ọdaran na lọ si ẹwọn oṣu mẹsan, ki Malamu Yahya fi ponun mẹwa (£10) tanran si Kotu, nitoripe ko wadi ọran nipa Obinrin na ki o to fẹ ẹ.

---

# Ọgbẹni Ọbande pada si Ipinlẹ Ariwa

Ogbẹni J. C. Ọbande ti iṣe Minista ati Alamojuto awọn Ọmọ-Ogun Naijiria ba Ọko ofurufu kuro ni Eko ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keta oṣu yi lati pari ibẹwo rẹ si apakan Ipinlẹ Ariwa.

Ogbẹni J. C. Ọbande yio si pada si Eko ni Ọla.

---

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

Yẹ irawọ rẹ ti ọsẹ yi wo, kio ba le mọ ibiti iwọ yio gbe ọrọ rẹ gba, nitori ogun agbọtẹlẹ ko npa Arọ.

Jan 20-Feb 18 (Aquarius) Ọsẹ yi dara gidigidi fun awọn Oniṣowo ati awọn ti ko ṣowo, ṣugbọn ọrọ edekoyede yio bẹ silẹ l a - r i n iwọ pẹlu Ẹbi rẹ

Feb 19-Mar 20 (Pisces) Iṣẹ rẹ yio pọ lọsẹ yi, ori rẹ yio walẹ, gbogbo ohun ti o ti jẹ iṣoro fun ọ, yio di irọrun. Ṣugbọn lo ọgbọn ori rẹ

Mar 21-Apl 19 (Aries) Bi o tilẹ jẹ wipe ọkan rẹ ko ṣe dee-dee lọsẹ yi, Iwọ yio ṣe orire.

Apl 20-May 20 (Taurus) Nigbati o ba nfẹ ṣe nkan ti ara rẹ kio ma fi ọgbọn ati lakaye gbe lati yanju rẹ, o dara kio ma lọ gba imọran awọn enia nla ki o to ma ṣe

May 21-June 20 (Gemini) Ṣọra, nitoripe gbogbo awọn ti yio rọgba yio ka, ko ni ifẹ rẹ. Nitorina, ọgbọn inu ku sọwọ rẹ bi o ba fẹ ṣọrọ obinrin, jẹki o to akoko ti orun wa loke

June 21-July 20 (Cancer) Nṣe ni kio gba ara rẹ mu giri ninu ọsẹ yi

July 21-Aug 22 (Leo) Gbajumọ awọn iṣẹ rẹ atẹhinwa, maṣe sọlẹ rara. kio si tọ ju ararẹ.

Aug 23-Sept 22 (Virgo) Ọjọ kan ninu ọsẹ yi dara fun ọ lati ṣọrọ nipa fifẹ Obinrin.

Sept 23-Oct 22 (Libra) Aye yio ṣi silẹ fun ọ lati rin irin-ajo tabi lati lọ wo enia.

Oct 23-Nov 21 (Scorpio) Gbogbo nkan ni yio tẹ ọ lọrun ninu ọsẹ yi, ọrọ ti o ba si sọ nii nwọn yio ma fi ara mọ.

Nov 22-Dec 21 (Sagittarius) Mura kio si ma jẹ igbadun ara rẹ nitoripe ariṣiki rẹ ko pọ to lọsẹ yi

Dec 22-Jan 19 (Capricorn) Iṣẹ pọ fun ọ lọsẹ yi lati ṣe iwọ yio gbadun obinrin ti o nba ṣọrọ ifẹ

# OFIN OLORUN NINU ESIN MUSULUMI

Lati owo:- KADIRI RASHEED - UD - DEEN

Aworan Olorun gegebi Iwe Alkurani ti so ni wipe on ni eni akoko on na si ni eni Ikehin, Ife ati anu, gbogbo awon to ba wa oruko na, lo nfa mora. Esin Musulumi so pe orisun alafia ati Iduno ni Olorun o si je Orisun Ibukun lati ibiti omi ife ti nsan ti anu si nsun jade bi odo ti nsan fun gbogbo eda.



Esin Musulumi ma nfun enia ni ireti ati ilosiwaju ninu ohun gbogbo, ko nje ki enia binu Aburadi tabi ainidi, o nje awon Musulumi fi oro won ti sodo Olorun Oba alaforiji ese ya a Oluwaro kere tabi o tobi.

Bayi ni Olorun so ninu Iwe mimo Alkurani w i p e gbogbo enyin eru Olorun ti e ti pa okan yin lofo laini ireti anu Olorun, alaforiji ni O b a Olorun, alaforiji ati alanu.

Nigbakigba ti elese kan ba yipada kuro ninu ese re to ba si pinnu po on ko ni de ibi ese na mo.

Gidigidi ni yio dun mo Olorun ninu, nigbana ni yio tan Ina Ibukun si eni na, gbo bi Anabi M u h a m e d ti wi.

Bi Elese kan ba ronu piwada tokan-tokan eyiyi dun mo Olorun ju igbati arinrin-ajo kan ti o ti sonu ti o tun wa ri oju ona lo,

Musulumi gbagbo pe, Olorun se eda enia ki o ba le ma fi oju anu wo o. O wa ninu Alkurani be.
Ko nse anu nikan soso ni Olorun ni si gbogbo E d a owo re, o si nferan won, on ni Oba Oludarijin ese ati Ife.

Olorun fe ki Ife wa larin on ati eda owo re Alkurani so bayi pe, awon ti o ba gba Olorun gbo ti o si nsise ododo ni Olorun nfi ife si ni aiya won, o ye ki Musulumi feran Olorun re ati eda elegbe re. Nigbana yio ma gbadun ara re Alkurani so pe bi o ba feran Olorun re ti o si ntele, Inu Re yio dun si o yi o si dariji gbogbo ese re nitori Oba alaforiji ati alanu ni Anobi Muhamad (P. B. O. H.) ti ko wa ni adura kan nitori iru nkan bayi:-

Enikeni ti o ba nfe imoran ti o daju nipa, gegebi a ti nse ohun ti awon npe ni Insurance ki o lo ri:-

Awon Ogbeni. **T. A. BRAITHWAITE**

**(Insurance Brokers) & Co.**

5, Williams Street
P. O. Box 785, Lagos Nigeria.
Telephone 21550, 21559.

Awa ni onisowo ti ise Asoju fun gbogbo awon Egbe onisowo Insurance Orisirisi ni ohun ti a le se Insurance le lori, die ninu won ni wonyi:-
A le fi emi ara eni se e.
A le fi dukia eni se e.
A le fi moto eni se e.
Ki jamba mase sele sini.
Ki ina mase jo dukia eni.
Tabi ki oko eni mase baje.
Gbogbo a w o n Onisowo Insurance ni a nse Asoju fun.
Lofe ni a nfi ona bi a ti nse e han awon to ba fe, yio si te Oluwaro lorun.

Oluwa wa ko wa lati ma fe o, ki a si ma [illegible]gbo awon ti o nfe wa nitori ki O ba le sunmo odo re ki O si ma fi oju ife Re wo wa ju ohunkohun lo.

# Irohin Imole Olowe

Lati owo:- CLAUDUS S. DADA.
No. 465 Omo Egbe Imole Aiye

I: Ibinu ko da nkan, suru ni baba iwa, Agba to ni suru ohun gbogbo loni.
R: Riro ni ti eda sise ni ti Oluwa.
O: Otito doja okuta owo lowo lanreke.
H: Hanha ni Opolo figa ju Alaamu lo.
I: Ife Afeju ni ewure fi iba oko re hu Irugbon.
N: Ninu ikoko dudu ni eko funfun ti jade.

I: Ijo ti o ba buru ni a amo eni feni
M: Ma fi o k o m e se ona ojo kan ni ako o
O: Obe tutu tan adahon mbuuia
L: Labalaba firare weiye kole sise eiye
E: Eni ba rora pa Eera yio ri ifun inu re.

GBANGBA DEKUN KEDERE BE WO!




OLUBORI EGBOGI "IKO"

THIOLYPTINE

Bi amodi "IKO" ti ojo re ti pe tabi ti o nyo o lenu fun nkan bi odun kan tabi jube lo awon egbogi robi-robi ko le se iwosan re rara, ma fi owo re se ofo mo.

Bere fun egbogi awon ara ilu Faranse ti nwon npe ni Thiolyptine Ojulowo haun-haun, atamatase egbogi fun Iko Fere, Iko tutu, Iko ona-ofun, Iko igba aiya, Iko-lile, Iko ti o ma nmu ki enia ma tu Kelebe nigbakugba lati inu fun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu ki enia ru polu. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine wo, iwo na yio ri iyato lara re ni kiakia. Igba aiya tabi ona ofun re ti o ma nho yo duro, "IKO" re yio si san patapata, Iwo yio ma jeun djaradara. Iwo yio si ma sun fon-fon pelu alafia ara.

Bere egbogi yi ati awon orisirisi egbogi Iko miran ni Sobu awon:— Price 10/6d Postage 2/6d

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# E ma ka Irohin Imole fun Irohin Aladun

## IWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

# 'KINIUN DAGBELEHE EKUTE'

Ẹ ba mi wa mọnyinmọnyin
fogungun o
Ẹ ba mi wẹran Agbo Foro
Ẹ ba mi waja fogun Onire
Ka wa igbin atata forişa
nla
Ntori aiye ndi rudurudu
Oju aro gbogbo awo
Boya ba ba şetutu
Boya ba ba bọ Irunmọlẹ,
aiye a yẹ ni

Mo de 'le Alara, awọn ni
Alara ti jade
Mo ni eruwọ, Alara ko
gbọdọ jade
Nwọn ni ilaju inu aiye
To nmu Titilọla rin hoho
To nmu iyawo Ọga wọ
Pata
On lo mu alara bọ si gba-
ngba
Mọ ni aiye nyi, aiye nfọ lọ
Nwọn ni ki kora da sọhun
Nwọn loju mi dudu, nwọn
ni ki nma lọ
Mo ni enia dudu ni Afọlabi
Boju ba dudu, binu ko du-
du
Ma dupẹ lọwọ Oluwa Ọba
Mo tun dele Lagbaja
Mo rọba ilu o fade dọbalẹ
ki baba
Mo ni lagbaja, ki la ti şe
Kiniun
To dagbelẹhe Ekute
Ki la ti şawonriwọn
To di itilẹ Alangba
Lagbaja ni ọjọ on kọ
Ẹjọ Ilaju to daiye ni
O ni ilaju aiye lo mu ọmọ
di baba
Ilaju aiye lo mole dadajọ
Tonişegun nşalalufa Ijọ
Edumare
Mo tun dele tamẹdu
Mo ri Bale ile o nşebẹ lo-
ri ina
Mo ni tamẹdu kilo ha şe?
Kini de so di ndi ninu
ile?
Kini de ti Bale ile ndi
agbọn onjẹ
Baba agba ni ki nşa dakẹ
O ni ki nma wo ni temi
O ni ohun to şe Ọkẹrẹ
to fi bo lori;
O mbọ wa ge Ọpọlọ ni iru
O ohun to şe Ila to fi ko
lori
Şo aşe ikan a wẹwu ẹjẹ.
O ni ohun şe Bale to fi
ndana nidi aro
Bo pẹ titi a kan gbogbo wa
Mo ni baba ẹ ma fi epe sọrọ
Şugbọn isiyi baiye ti nlọ
o su mi
Ilaju lo mu Ọga ilu denu
igbo
Ilaju lo mu alaimọkan atijọ
dọga wa
Ilaju salaimọkan dọga, o
nlọda fọba ilu
Ilaju salaimọkan dolori
O dọba gbogbo wa
Şugbọn:

ORIN:- Ẹ şe re ko dara
Ẹ şe re ko dara o
Ajigbọtoşa ẹ şe reo.

## Ọkọ-iyawo ati ọmọ ọdun Mẹjọ sọnu

**ILESHA:-** Idaamu nla ba gbogbo awọn ara Abule-Bode, ni agbegbe Ilesha nigbati Ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Ganiyu Adekanbi ti o nşişẹ Gbẹnagbẹna ko pada wale lati ile-işẹ rẹ ni ọjọ Aje ti işe ọjọ keji Oşu yi.

Adukẹ ti işe iyawo Ọkunrin na sọ fun awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ Ilesha wipe, ni kutukutu owurọ, ni ọkọ on jade ni ile, ti o si dagbere pe on nlọ si ile-işẹ on, o si gbe apoti irin-işẹ rẹ dani.

Şugbọn nigbati o to asiko lati de, ti on ko si ri i ni on ba lọ si ọdọ iya rẹ ti on si sọ fun un. Lati igbana ni on ati iya rẹ si ti wa ọkọ on lọ si ile-işẹ rẹ şugbọn awọn ko ri i lati igbana, titi di oni.

Lẹẹkẹẹ ni awọn Ọlọpa si jade ni Teşan ti nwọn si bẹrẹsi wa a. Nigbati nwọn de Bode (ile işẹ rẹ) nwọn pade iya kan: Sidikatu ati ọkọ rẹ Muraina ti nwọn nwa ọmọ wọn, Wosilatu Adebisi ẹni ọdun mẹjọ.

Baba ọmọ na sọ fun awọn Ọlọpa wipe, ọmọ awọn sun ni ile, ni awọn ba sare lọ si oko, sugbọn nigbati awọn de lati oko, awọn ko ba ọmọ awọn mọ lori ibusun. Awọn Ọlọpa ati gbogbo awọn enia abule na a ni nwọn nwa ọmọ-ọdun mẹjọ ati Adekanbi ti o şọşọ gbeyawo na. Şugbọn nwọn ko i ti gburo awọn mejeji.


## KẸRE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin mo ba yin yọ ẹ ku afojuba Egbogi pataki ti a şe Iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn Ajakalẹ Arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o wọpọ ni ode isinsinyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ. TULU. LUKULUKU. OTUTU. IGBA-AIYA DIDUN. ARA RIRO. ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO.

Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi, Irohin ko to afojuba Ẹ bere iwe ti ẹ o fi lo Egbogi na lọwọ ẹniti o ba ta fun yin. O daju hanwuu Ẹ o ri işẹ rẹ lẹhin Işẹju mẹdogun ti ẹ ti lo.

Bere lọwọ awọn Onişegun adugbo rẹ.

**Distributors**

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, BISHOP STREET, PHONE 23745
LAGOS


## Nigerian Ports Authority

### INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such Scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st July, 1962 to 31st December, 1962, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed tender form should thereafter be returned to the Secretary in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Friday, 20th July, 1962.

The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tenderer, who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

During the six month period indicated, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is made available for sale (with the exception mentioned above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 729
4th July, 1962.

*Printed and Published by:— MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos. Olotu: E. A. Adeniji, 24, Ollyide Street, Odu-Abọrẹ Mushin.*